To the Chief Secretary to the Government

# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead

Vol. VI No. 266 SATURDAY, MARCH 17, 1928. 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.


## *White's Radical Gonkiller.*

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea* ]

MAR. 1928

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases, such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs,** and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

---

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[ *Fun Atọsi lailai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si nję ki o ri aye wu arun mi silę.

"AWA O MA JO, AWA O MA YO, NI"

Aga ati Asia (*Flags*) ti Germany lorişirişi wa fun hihaya ni No. 3, Docemo Street, Lagos. Aga ati Asia wọnyi dara fun akẹkẹyẹyẹ pupọ, fun Igbeyawo Wolimọ, Ijọ-Ọdun Musulumi, tabi ti Kiriyo, fun ere nile Egbẹ, ati orişirişi ohun ayọ miran.

*Terms very moderate*

for particulars, please apply at :—

EKO-ATOPO CHAIRS & FLAGS SUPPLY

Office :—

No. 3, Docemo Street,
P.O. Box No. 505.
Lagos, Nigeria.

---

**Coffins to suit your Taste**

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at J. B. da Silva, 40, Odunlami Street, Lagos: also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

---

## Ero ya wa ra

ADEBOYE ŞOLANKE Onişowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikan-ọkọ, Iṣo lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọsan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awọn ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa 'okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Şọbu rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

**Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ.**

---

**Are you a Mechanic ?—If so you must want Tools, now or soon!**

**Do you intend to put up a house ?—** Then you will require Builder's Hardware!

In either case you cannot do better than call at

**B. C. Vaughan's "Excelsior" Stores**

at Agarawu Street, Lagos.

Where the largest and most varied assortment of Artisan's Tools and Building Materials in Lagos is stocked.

Quality to satisfy all demands, and prices to suit all pockets.

*Special discount to Traders and Wholesale buyers.*

---

**J. C. VAUGHAN**

Ti ile ọja Sheffield ni ita Kakawa ati ile-ọja *Excelsior* ni ita Agarawu ni orişirişi ati oniruru ohun kikọ 'le fun tita ni owo-ọpọku-ọyọku.

Ilekun awọn ile-owo mejeji wọnyi şi silẹ fun awọn Ọmọle ati awọn Gbẹnagbẹna : bi o fẹ da awo ni o, ero-ija dida'wo ko ni jẹ ọ ni'ya lati ra nibẹ :

Alagbẹdẹ Wura tabi ti Fadaka ni ọ ni o, gẹgẹ l'oşe fun ọ lati re yan irin-işẹ tirẹ nibẹ ba kanna

Owo Ogbẹni J. C. Vaughan ti di Owo Ata[...] Ajanaku lọjọ to ti pẹ : bi Ọgẹdẹ si ni Owo rẹ ngba kakiri ibikibi. Agbẹ ni ọ kai ! bi o ri orişirişi Oko[...] ti o ri ra nibẹ ha yio şe ọ.

Sure tete iwọ Ọmọle, iwọ Gbẹnagbẹna, iwọ Aranbata, iwọ Asenjẹ iwọ Ageginigbo (*Sawyer*) Alagbẹdẹ Wura, iwọ Alagbẹdẹ Fadaka, iwọ Agbẹ re ba ori're tirẹ pade nibẹ.

**Owo-lọwọ ni gbogbo ọja meremere ibẹ.**

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RE

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

# GBOHUN-GBOHUN.

## EPARIPA, AWỌN T'O NWA 'ṢẸ DI BOMBATA.

A gbọ pe awọn ọkọnrin ti nwọn lọ ṣe idanwo ni lọlọyi ni ibi-iṣẹ awọn Ọlọkọ Ọba (*Marine*) to iwọn ọdunrun enia ati pe awọn mẹtalelọgbọn pere ni a sọ pe nwọn yege idanwo na: Dokita si ni lati yẹ awọn mẹtalelọgbọn na wo ki a to gba wọn si iṣẹ; Baba nikan lo mọ melo lo ma ku ninu awọn mẹtalelọgbọn yi lẹhin igbati Dokita Ọba ba ti yọ'ri yiyẹ wọn wo tan. Eko, ẹ ko wa ri pe ogun airi 'ṣẹ ṣe de, ọpọlọpọ awọn ẹlomiran lo ma wa nisisiyi ti nwọn ko mọ ibiti nwọn le wọ lati wa iṣẹ, Baba maṣai da'wọ paṣan inira wọnyi duro.

## O DABỌ O.

Ọgbẹni P. St. Mathew Daniel, *Registrar*, yio lọ si Abẹokuta pẹlu Justice T. D. Maxwell l'ọtunla fun Kotu *Assize* ti nwọn yio ṣe nibẹ

---

## ASỌTẸLẸ LỌRỌ ANA.

### NIPA IṢESI AWỌN OYINBO ONIṢOWO.

Lati ọwọ KEKERE AWO.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*,

Mo bẹrẹ f'oji,

A tilẹ nwi a nsọ wipe irufẹ ipo ti ọran owo ati iṣẹ mbẹ laseko yi ko yẹ arara, ati pẹlu a si nfẹ ki awọn Ijọba dide si gẹgẹ bi alagbara lati ṣe ṣawura pataki le e lori.

Bi a ba sọ ọ siwa o yẹ ki a tun sọ ọ sẹhin, ki o ma jẹ wipe awẹ aṣọ kan li a nmu ran.

A nja fun awọn oyinbo oniṣowo ẹwẹ a si nja fun awọn enia dudu pẹlu, ti a ba ja fun awọn mejeji bayi tan ti gbogbo nkan ba bọ si eto pataki daradara to! o daju pe ko si ewu fun awọn ọmọ wa ti nwọn nringbanraye ti ai ni ipin iṣẹ lọwọ kiri mọ, ọkan olukuluku yio balẹ wọkuwọku bi ọkan tolotolo, bẹ bi ọkan awọn ara ilu ko balẹ inu ilu kole dun arara.

Ọn awo li a ngba ja fun awọn oyinbo oniṣowo ati awọn enia dudu pẹlu? Idahun fun u ni wipe a kigbe fun awọn Ijọba gẹgẹbi Alakoso wipe oye ohun ti a ri fun ilu leyi, oye na ni pe, gbogbo nkan ti bajẹ nipa owo ati lori iṣẹ ṣiṣe, eyi ti a ṣi nfẹ ki awọn Ijọba ba awọn ẹniti awọn oniṣowo fi ṣe aṣoju wọn si Kansulu ṣe ṣawura pataki bi Ijọba yio ti fi eyi si aniyan, bi nwọn ikoi si ti gbọ ohun ti a nsọ arara, a koi ti mọ ṣugọn bi o ti wu ki o ri a ko le ṣẹṣẹ ma tutọ soke ki a ma fi oju gba a lojojumọ pe o yẹ ki Ijọba dide si ohun kan lati ṣe, ni iwọn-gbati o ba ti jẹ wipe, Ijọba ni Alakoso ilu, abẹ wọn si ni ilu wa, ẹtọ ni wipe nwọn ni lati ma mọ ohun ti o nlọ ni ilu, nwọn si ni lati ma mọ ohun ti o nkọja wa si ilu.

Bi Ijọba ba ni lati ma ri gẹgẹbi a ti la a yi, bi ilu ba nfẹ eto pataki kan, o yẹ ki a fi siwaju wọn gẹgẹbi ẹtọ, ko si ohun meji ti o nda awọn ilẹ enia dudu làmu nisisiyi papa ilu Eko ti o kọja ti ai si owo ṣiṣe ati ai si iṣẹ ṣiṣe ti a nwi yi.

Bi iṣẹ ati owo ba nlọ tara, ori ilu ni lati ma ya, gbogbo nkan ni lati ma gun lọ gere, ṣugbọn awọn apakan njẹun fa awọn apakan nrunpa fun ebi, tabi nwọn nlagun tagbara-tagbara, ki nwọn to le jaja ri okele owrọ bu si ẹnu, ọna wo ni ilu le gba ti inu rẹ le fi dun?

O daju pe inu ẹniti ko ri iṣẹ ṣe ti ko si ni okowo kan lọwọ kole dun arara, bi a ba si ni a ri ẹniti o le sọ wipe eyi ti a wi yi ko ṣe nkankan fun on, o purọ ni, bi ko tilẹ ṣe nkan fun u, o daju pe ti oṣu ba pari, ti o ba gbọ wipe awọn oṣiṣẹ olukuluku wọn ngbowo, ori rẹ ni lati wu pe on bi on ba nbẹ lẹnu iṣẹ, on na ma ni lati wa lara awọn ẹniti yio gba owo loṣu, bi o ba si jọ Kafinta tabi Birikila, bi ko tilẹ ri ti oṣu gba, yio ri ti Satide gba.

Awọn enia ti o nbẹ ni arin ilu lo njẹ ilu, eyiti ẹlomiran mọ si ilu, ilẹ ni iyẹn ni nwọn npe e nitorina awọn ẹnti o ngbe inu li a nba wi, boya ọpe ẹlomran le sọ wipe nigbati a nsọrọ bọ ki to wa fi ẹnu kan ti owo-oṣu koṣe owo-oṣu inu ilu kole dun li a ntẹnu mọ.

A ri gedegbe pe lai si tabitabi ọrọ ti a nsọ yi ko fi ara sin fun ẹnikẹni, o han fun taja-tẹran, o han onile ati alejo koda titi o fi kan eweko igbẹ pe ai si iṣẹ ṣiṣẹ ati owo-ṣiṣẹ lo ndamu ogunlọgọ enia lode ti oni.

Wayi o, ki a wa fi ohun ti a gbọ a ri pe awọn oyinbo onişọwo papa nşe aşe han, gẹgẹbi asọtẹlẹ ti inu wosika wa lọsẹ kẹta. Eyiti awọn oyinbo onişọwo papa nşe, o kọ adiẹ lẹsẹ.

Bi ilẹ ti nmọ ti ilẹ nşu bẹni awọn oyinbo onişowo nşe şawura (Conference Agency) firifiri, o si daju pe nwọn ko jẹ şe apejọ ti yio mu ki owo ni lati ma jo ajorẹhin bi ina Hotọnu, ani wọn ko jẹ şe apejọ lọna ti nkan yio fi bajẹ fun wọn, bikoşe lọna ti nkan yio fi ma lọ letoleto, wahala pupọ li nwọn si nşe nipa eyi lojojumọ, şugbọn sibẹsibẹ awọn enia dudu ko mọ yi, irufẹ wahala ki wahala eyiowu ti nwọn le şe, nitoripe nwọn ki ipe wọn si, bẹni nwọn ki i si ifi aşiri apejọ wọn han awọn onisowo enia dudu gbogbo ti o nbẹ labẹ wọn.

Bọkanran eyi o dabi ẹnipe apo ara wọn nikan li nwọn njijadu si.

Ni iwọn ọdun diẹ sẹhin tabi laseko ti iwe owo şẹşẹ yọju fun nina, owo nlọ daradara, awọn onidọhọ nri Ekurọ, Epo ati Koko ta, awọn oyinbo onişowo si ngba awọn ọja wọnyi daradara, kẹrẹkẹrẹ nwọn ndin'wo ọja rira wọnyi ku. lati igbana ni okuta fi nba awọn ọja ni olukuluku fi nşubu lori owo ko ni iye awọn oyinbo onişowo ti nwọn ko igba sile lai rotẹlẹ ti a ko tilẹ gburo wọn nnrinfiorin mọ arara, ni aseko yi a tilẹ gbọ wipe na bi o ba ti wu awọn oyinbo wọnyi ni nwon nra Ekurọ, ojojumọ ni nwọn fa owo rẹ sẹhin, lai si tabitabi eyi dabi ọja tulasi fun awọn ẹniti o nmu ọja wa fun wọn, nitori wọn ko ri ere to tẹrun jẹ lori ọja wọn, agbarakaka li nwọn tilẹ fi nri oju owo ọja wọn, irufẹ şişe bayi o yẹ ki o jẹ ohun ti a ni lati fi si eto daradara.

Awọn oyinbo şi şabu wọn silẹ nwọn si ko awọn oja sibẹ fun tita, iye ti o ba wu wọn ni nwọn ma bu fun awọn ọja, ẹniti o ba fẹ ra ti ko ba tẹl run, ki o fi silẹ, ki işe awọn ẹniti yio ba wọn ra ọja ti nwọn ko si ni Şabu li yio diyele ọja ti oluwarẹ fẹ ra, agbẹdọ arara awọn fun ara wọn ni nwọn ndiyele ọja wọn, nwọn si ti fi ero lu ọja wọn; nwọn to mọ iye ti o ba de ninu iwe-ẹru (Invoice) nwọn si ni lati mọ iye ti yio ku si fun gigunlẹ si Bode (landed cost) ki nwọn to wa fi ero si bi nwọn yio ti ta si ati bi wọn yio ti jere si.

Bi o ti wa ni liki lo wa ni gbanja, bẹni o nbẹ fun awọn ẹniti o ni oko, ti wọn si gbin ohun ọgbin sibẹ lati ta, ki ebi ma ba pa wọn, wahala pupọ si ni nwọn ni lati ma şe sori rẹ, ki ohun ti nwọn gbin to le ye, lẹhin ti nwọn ba si ye yiyọ Ekurọ Epo Koko tabi awọn nkan miran ti oyinbo ngba, nwọn ni lati şe işẹ daradara le wọn lori, siwaju ki nwọn to mu lọ fun tita, bibẹkọ awọn oşişẹ ti awọn oyinbo gba sidi işẹ na ki yio gba a, eyiti ko ba si şe akiyesi daradara, ti o gba ti o sanwo rẹ, bi awọn Alabojuto (Inspector) ti Ijọba yan ba wa yẹwo, ti ko ba dara, ẹniti nwọn fi sidi işẹ na şọti (short) ni iyẹn; lori gbogbo wahala ti awon olọja wọnyi ni lati şe, ira bi o ti wu mi ni nina ra a, lo dara ni tabi ira ti awọn oni 'kan yio fi jere leri ọja wọn? bi o ba jẹ wipe ira ti ọlọja fi le ri ere jẹ leri oja rẹ lo dara, ko ha şe ti awọn oyinbo fi nra Ekurọ, Epo, Koko tabi awọn nkan miran bi a fi agbara ra.

O yẹ ki a fi ero si ori ọja wọnyi o pẹlu ohun ti o şe idawọkọ işubu owo tabi ailọdede, nigbati owo ko lọ dede ni ko fi si işẹ şişe ni ilu.

Awọn onişowo enia dudu tun nkigbe loto lọ ara wọn wipe awọn oyinbo ndi ọja awọn lọwọ.

Ni ọjọ Ejirin nisisiyi, o ni iye awọn oyinbo ti nwọn lọ si Şọbu sibẹ lati ma ta ọja, bẹni a si gbọ wipe nwọn şe idọhọ sibẹ pẹlu lati ma ra awọn oja Ekurọ, irufẹ ọja kanna ti awọn onibara wọn ra lọwo l'Eko na ni nwọn ma ton lọ patẹ rẹ awọn si ni lati din'wo ti wọn ju ti enia dudu lọ, enia dudu ti ko ba si jẹki owo ti wọn ba ara wọn mu, kole pa kobọ aladọjọ, alalikuwa, nwọn ma ti ta oja wọn fi fun awọn onibara lati ile lọ, ti o jẹ wipe agbara ni awọn tikalara wọn yio fi ta lohun lati ri bi elo kan lori rẹ, idiwọ nla patapata ni awa mọ eyi si, lẹhin a o si jẹ ohun işoro fun awọn ẹniti o nti ile lọ ra Ekurọ ni Eururin tabi Agbadayigi ati Ọjọ lati ri ọja ra debi ti nwọn yio fi ri bẹnbẹ şarawoyẹ, ti wọn—eyiyi ni ere ti nwọn ni lati jẹ lori oja ti nwọn ti ile wọn şe wahala lọ ra ni awọn ọja mẹtẹta ti a darukọ yi.

O yẹ ki Ijọba dide is eyi lati şe eto pataki, gbogbo ọgbọn agbọnju ti awọn oyinbo onişowo papa ngbọn yi lo tubọ mu ki gbogbo nkan lọ silẹ nigbati awọn kan ngbọn si apo ara wọn nikan, ti nwọn ko fi ti ẹlomiran kun u, kini gbogbo nkan ti şe le lọ letolete?

Ati pẹlu awọn akowe to nta ọja ni Şọbu awọn oyinbo larin ilu ọrẹ wa kan nfi oye nipa aini itẹlọrun si işẹ awọn oyinbo wọnyi han, bayi pe awọn nri ọpọlọpọ wahala lori işẹ wọn.

Awọn oyinbo nsan Ponun mẹta tabi jubẹ lọ diẹ fun wọn loşoşu, bẹ ẹlomiran ninu awọn akowe wọnyi yio fi nkan ẹdẹgbẹta titi de ẹgbẹrun Ponun duro, ki nwọn to le ri işẹ na şe.

Lehinna nwọn ni lati ta ọja to ẹgbẹrun Pọnun nwọn to bẹrẹsi fun wọn ni ere-iṣẹ (Commission) lori ọja ti nwọn ba ta; Kọmiṣanni yi ko Ponun kan lori ogun Pọnun lọ, Pọnun mẹwa lori ẹgbẹrun Pọnun, bi nwọn ko ba si ta ọja loṣu kan, to iye ti nwọn ni lati gba kọmiṣanni yi, a jẹ wipe owo-oṣu nikan ni nwọn ma ri gba sibẹsibẹ oyinbo ni lati ko ibere pa wọn pe kiloṣe ti nwọn ko fi ta, pẹlu aroye pe nwọn nfẹ ki awọn ma san owo Ṣọbu danu ni, ninu awọn akọwe wọnyi, eyiti o ba si ṣeṣi gboju gbaiya ta ọja awin si ode, ti o ba to aseko lati ka ọja, bi ọja rẹ ba lọ din to adọta pọnud pẹarẹn, o di wipe ki nwọn ti Ṣọbu titi akọwe yi yio fi sanwo yi, ti nwọn ko ba si tete ri akọnta na gba, ojiji ni nwọn ma pe ẹjọ si Kotu.

Ninu awọn ọmọ wa ti o si nṣe irufẹ yi fun awọn oyinbo wọnyi ni ilẹ yi le jẹri si ohun ti a nwi yi.

Lai si awin ninu ọja wọn, o daju pe nwọn kole ri ọja ta bọrọ, bi ọja ko ba si ta kẹ, nwọn kole ri kọmiṣanni wọn gba, awọn oyinbo ie kẹ, nwọn ko jẹ sọ wipe awọn yọda fun ẹnikan pe ki o ta ọja awin; wayi o ara wo ni ẹniti o gbe ogidilcje irufẹ chun ini tamtam bẹ duro le fi pọnun mẹta oṣu da?

Ẹ jẹki a gba gbogbo ọrọ wọnyi yẹwo daradara, ara ohun ti ko jẹki iṣẹ le lọ dede na ni a nfi oye rẹ ye ara wa yi, o tọ wipe ki awọn oyinbo-oniṣowo gbe eyi yẹwo daradara.

Gbogbo nkan ti o delẹ yi, ki iṣe ohun ti a le mu kukun lati ṣe; o gbẹsọ, nitori o ti kọja ala; lọsẹ to mbọ a o fi aṣiṣe awọn enia dudu han wọn nipa iṣe si wọn.

## AṢARAYILU TO NJẸ IKU,

Lọjọ ti Ọlọrun ti da Anọbi-Adamọ, Baba nla wa lo ti da iku mọ olukuluk wa, bi o ti wu ki ẹnikan le ba Ọlọrun ṣe ọrẹ to ko jẹ bi ẹnikan ṣọrẹ pe ki o jẹ sugada sinu aiye titi lai ni ipẹkun.

Awọn yoruba nsọ wipe ọkankan ni a wa si aiye ọkankan ni a o si pada lọ, ko si ẹniti yio mu aiye ra ninu wa.'

Lori chun ti awa ẹda le ma ṣe ninu aiye, ti ọran ba de ibi ti iku yi, yio mu ki arẹ mu wa, iku ko da ọjọ, arun ko da oṣu; awọn ẹlomiran nsọ wipe, awọn ni amoye to nmọ ọjọ ti ẹnikan le popada, koda a tilẹ gbọ wipe nwọn ni iwe rẹ ni ilu oyinbo, a ko mọ awọn oyinbo ti nwọn sọ wipe nwọn ni iwe rẹ lowo yala Igẹsi, Faranse, Jamani, Aguda, Indian, Amẹrika tabi awọn jakan-jakan.

O da wa loju wipe ti ẹlomiran ba le mọ ọjọ ti on yio ku, tabi ti ẹlomiran bi le jaja ni iwe rẹ lọwọ ọpọlọpọ ẹlomiran ni iba ti gbidanwo lati mọ ọjọ ti on yio popoda laiye, ki on ba le mọ ohun ti on yio ma hu ni iwa titi Aṣarayilu yio fi de.

Ati pẹlu bi Aṣarayilu ba nṣe ẹniti enia nba ṣọrẹ ni ọpọlọpọ ẹlomiran ni iba ti wa owo lọnakọna lati yọ ararẹ lọdọ iku, nitori ki on ba le mu aiye ra, ki idajọ ti on ba le ba on laiye ki iya on ma ba pọ to bẹ, nigbati ko wa ṣeṣe yi nkọ, ewo ni a o ṣe o ẹnikeji?

Igbagbọ ọpọlọpọ ni wipe ninu ile aiye yi ni a o ti ṣe idajọ ẹlomiran ẹwẹ awọn si nsọ wipe idajọ mbẹ lọrun, ṣugbọn on ti on bi ṣe ni aiye, bi awọn ba de ọrun lọhun awọn yio jumọ ma lọ ro o.

Nitotọ idajọ mbẹ ni aiye nihin fun awọn ẹniti o lero bẹ, ṣugbọn nwọn ba le sọ wipe lati inu ile aiye wa yi, ni Ọlọrun yio ti ma ṣe idajọ ẹlomiran iba dara.

Ki a tun wa fun awọn ẹniti o gbagbọ wipe idajọ mbẹ ni gasikia ni ọrun lesi lori eyiti nwọn nsọ wipe o di igbati awọn ba de ọhun, o mi ṣe o! ko da wa loju pe irufẹ awọn ẹni bẹ gba Ọlọrun gbọ gidigidi, nitoripe ti nwọn ba gba a gbọ o yẹ ki nwọn mọ dajudaju pe ko si igbati Ọlọrun ko le ṣe idajọ fun olukuluku wa fi iwọn igbati o ba ṣi nmi loke epẹ, ki o to wa kan ti ọjọ idajọ papa.

Bi o ba is jẹ wipe ọpọlọpọ wa gba Ọlọrun gbọ ẹwẹ ti a si ni ibẹru gẹgẹbi O ti nfẹ, a ba dẹkun iwa buruku ti o kun fun ọpọlọpọ wa lati ma hu ninu igbesi aiye wa, papa awọn ẹniti nwọn nsọ wipe awọn ka iwe mimọ Ọlọrun perepere, ani ti Bibeli tabi Alukurani nsọ kulukuta lori wọn, ti nwọn fẹrẹ le ma ka loju 'ran.

Ti irufẹ awọn ẹni bẹ ba fẹ di ẹlẹmi eṣu lati ma huwa buruku gbogbo, nwọn a gbe iwe mimọ Ọlọrun sonu, lati fi gbagbe wipe ko si iku mọ, bi iku ba tilẹ wa, ki iṣe aseko ti awọn si nhuwa obilẹiẹ tabi iwa janduku gbogbo ti ko to ṣuna fun Ọmọluwabi, nigbati iwa buruku wọn ba wọ wọn lẹwu tan, ti awọn na si ti gbagbe wipe iku mbẹ Alumotu, ni jagun ma fi waya ṣọwọ wipe on mbọ ki o mi mura, nigbati atẹgun rẹ ba ṣi nkọlu ẹlomiran ti iku ti de lẹwon lẹse ni a o ma sọ wipe ọ ndaku o ndaji ti o ba di ọjọ ti jagun papa da ba pe lo ma yọ si oluwarẹ gburẹ pe aseko to, bi enia gbe ẹdun-ara mọkanle-lerugba mi, ki o tun di gbogbo Ajapa ti Ọlọrun da sinu igbo si igba-aiya aiya rẹ ni lati ja idi rẹ ni lati di omi pẹlu ohunkohun eyi o wu ti oluwarẹ le jẹ si ara tabi ki o fi dabo bo ararẹ nitori iku ko di ti iku Asarayilu lọwọ lọjọ yi, kiakia ni gbogbo rẹ ma di omi-oju mọ oluwarẹ lọwọ.

Nitorina anu ṣe ni fun ọpọlọpọ wa, ti nwọn jẹ oye songiba sinu aiye lai ni ireti pe iku mbẹ nitorina ṣe iranti pe iku mbẹ Alumotu.

## OLOGBE DOKITA JOHN RANDLE.

Anu nla loṣe wa lọjọ kẹtadinlọgbọn oṣu February to kọja yi, ti nṣe ọjọ Monday nigbati Ọgbẹni Henry Carr (Balẹ ọkọ-ilu ri), tufọ Ọgbẹni Dokita

John Randle, ti ile rẹ mbẹ ni ẹgbẹ ile ifiwe ṣọwọ Post Office ) Lẹhingbẹti.

Gẹgẹ bi a ti gburo iwe iku ẹni yi ti Ọgbẹni Carr fi tufọ ni wipe nwọn yio gbe oku na lọ si Ṣiṣọ Alagogo lọjọ keji rẹ dede mẹsan agogo owurọ, ti nṣe ọjọ kejidinlogbọn oṣu February, lati ibẹ lọ si ile isinmi rẹ—Ikoyi Cementary.

Lai si tabi-tabi ṣaṣa enia ni ko mọ Ọgbẹni John Randle nigba aiye rẹ gẹgẹ bi o ti jẹ larin ilẹ yi, on lo jẹ Giwa fun Ẹgbẹ kan ti nwọn npe ni "The Peoples Union" ati Reform Club, Ẹgbẹ "Peoples Union" dajudaju ko di igba ti a ba ṣẹṣẹ sọ ki a to mọ wipe nwọn ko ṣe dede pẹlu Ẹgbẹ Bombata (The Nigerian National Democratic Party) Ẹgbẹ ayanfẹ awọn ara ilu Eko ati ni awọn igbereko rẹ.

Bẹni a si mọ wipe nigbati a ni ko si iṣedede ninu ohun kan, a mọ itumọ rẹ si wipe ifẹnuṣọkan ni ko si nibẹ, ai fẹnu ṣọkan na lo si mba ilu yi ja loni ewẹ lo fi jẹ ki gbogbo rẹ di rudurudu bayi.

Enia pataki papa ni ologbe Randle jẹ, o si jẹ ojulowo Dokita hanunhanun o ni Ọro (wealth) lọwọ ni nwọn ibi ti ọmọ enia, o fi ararẹ han ni igba aiye rẹ bi ẹniti o ni itara si ọran ilu o lọ si ilu Oyinbo kumọna, o si fi ẹnu kọ ọrọ ilẹ yi lọhun ni aseko ogun Ajakaiye, o sọ ọrọ gbangba nla kan ni Ita Tinubu eyiti o fi ṣe adura fun Ijọba Gẹsi pe ki awọn le ṣẹgun ọta.

Enia ko le wa ki o ma ni iwa omiran eyiti yio lodi si ifẹ ọmọ Anabi Adamọ, bi o ti wu ki oluwarẹ ni iwa rere to, nitorina titi ọjọ mẹta lagbara Soko, a o ṣe Aṣanyan ọrọ pataki nipa iwa ologbe Dokita John Randle ni igba aiye rẹ. Ki Olorun torijin o.

## Ẹ KU IPAMỌ ỌDUN O!

A gbọ lẹnu awọn Musulumi pataki pe lọjọ Jimọ to mbọ ọjọ kẹtalelogun oṣu yi ni nwọn o Kirun Ọdun wọn *Eidil Fitri* bi ko ba si dāsi.

A sọ fun wa wipe ti o ba di ni dede agogo mẹsan Chief Lemọmu Ligali—Olohun iyọ yio gbera ni ile pẹlu awọn Ẹmẹwa rẹ lati lọ ṣe Alhamdu-li Lahi ni ẹhin Odi.

A ṣeranti pe Irun ti awọn Musulumi ki gbẹhin eyiti nwọn npe ni Ọdun Ileya, ọjọ Jimọ bayi lo bọ si ṣugbọn awon Jamat meji fi ake kori pe agbẹdọ awọn ki yio kirun lọjọ Jimọ bikoṣe Satide ọjọ keji rẹ, nwọn ṣe akatakiti yi titi lẹdọ Oyinbo Aṣoju-ilu pe ki nwọn le ba won yẹ Irun na si ọjọ Asibi bi o ti jẹ wipe ọjọ Jimọ ni Sati ṣe to si! gbogbo rẹ kisi ti nwọn di igba rẹ fọ mọ wọn loju, itiju pami arẹ epe ni nwọn ba jade lọjọ Asibi, nigbati nwọn ko mọ eyiti nwọn ma ṣe ni nwọn ni ki awọn Alagbe ma wi niwaju wọn pe, ẹniti o Kirun lana Ṣango lo bọ ọ, dipo Sub-ana-li-lahi ti Tira sọ wipe ki nwọn wi.

A si ti ni igbagbọ wipe nwọn ko jẹ ro irufẹ bẹ ṣ'oro mọ lailai, bi bẹkọ ọjọ tun de ibi ana, Jimọ ni "Yidi" ewo lewo ẹnikeji?

Emi ni tiyin nitotọ,
KEKERE AWO.

---

## OLUSAKIN'S COLUMN.

### The Archdeacon of Lagos.

At the Lenten Service held at St. Paul's Church Breadfruit on Wednesday, the 7th instant, the Venerable Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi, L.th., preached an impressive sermon to a large congregation.

### A Great Lawyer's Sacrifice.

There are some attractive plums in politics as a career but few financially good enough to induce a man easily to give up voluntarily an income of between £25,000 and £50,000 a year. Yet Sir John Simon, K.C., has done it twice. Nearly eighteen years ago, when he was said to be making £25,000 a year in the Law Courts, he gave it up to become Solicitor General. His political career was almost as sensational as his legal success. During the war he had become Home Secretary, but he resigned because he did not agree with conscription. For ten years he has been a Lawyer again, and his income is said to be £50,000 a year. Once again he throws it up for politics—to become Chairman of the India Commission.

### K.C.'s Monster Fee.

A fee of £53,000 with a "refresher" of £200 a day during the three months that he will be away, is to be paid to Sir Leslie Scott, K.C., M.P., for legal work which he has undertaken in India. His total earnings for the three months will therefore be more than £70,000—believed to be easily a record fee received by any barrister.

He has been engaged to advise the Indian States and princes in connection with the Indian Commission. Sir Leslie Scott was Solicitor-General in 1922, and is one of the best known K.C.'s at the Bar.—*Tit-Bits February 11 and 18 1928.*

### Resumption of Duty.

Mr. E. Ọlakunbi Oke, Foreman Printer, Railway Press, Ebute Meta, who has been on 2 months' leave, has now resumed his duties as from the 13th instant.

### The Wesleyan Boys' High School Golden Jubilee, 1928.

There will be a Garden Party of the Old Boys in the School Compound to day the 17th instant, from 4.30 to 6.30 p.m., by invitations only.

### In Honour of Mr. Sydney Fairman, Storekeeper Nigerian Railway.

There will be held a Farewell Reception in honour of Mr. Sydney Fairman, Storekeeper, Nigerian Railway, by the African Staff of the Stores Department, on the Railway African Staff Tennis Club Grounds, Ondo Street West (opposite Wesleyan Church) Ebute Metta, on Tuesday, the 20th instant, at 5 p.m., special invitations.

To the Secretary, Mr. Ọlamide Ajayi, ẹ ki ipamọ.

**Mr. Bottomley Wins.**

HIS LIBEL SUIT WITHDRAWN ON ARRANGED TERMS—PAYMENT OF DAMAGES.

A settlement was announced before Mr. Justice Horridge in the King's Bench Division yesterday of the libel action brought by Mr Horatio Bottomley against the *News of the World Ltd.*, and Henry James Honston.

The record was withdrawn on terms arranged.

Mr. Connyns Carr, for the *News of the World* asked that a statement should be read without comment.

It was to the effect that five statements in articles, of which Mr. Bottomley complained, were written and published in the full belief of their accuracy.

Defendants, however, were satisfied that they could not be substantiated, and had agreed to make a payment by way of damages in full discharge of all claims. *The Daily Mirror, 14/2/28.*

**Death of Bishop Chavasse.**

The death of the Right Rev. Bishop Francis Chavasse is announced.

The late prelate was in his 82nd year, and for 32 years he was Bishop of Liverpool.

---

Si Oniwe Irohin Eko Akete, mo juba o,

Jọwọ fun mi laye diẹ kiun, ninu Iwe Irohin rẹ oniye-biye, lati fi da akọwe rẹ Riro nitenia Ọlọrun Loluṣe, lohun nipa ibere rẹ to bere lọwọ Ẹgbẹ mi The Igbajọ Union ninu ọrọ rẹ ti Satide ọjọ kẹwa Oṣu yi (10th March 1928) pe bi irọ ni on pa bi irọ kọ, wipe Ẹgbẹ mi na nfẹ fi Ontẹ Ọba tẹ Ẹgbẹ wọn (that the Igbajọ Union is willing to register their Company).

Otitọ hanwun-hanwun ni wipe Ẹgbẹ mi fẹ fi Ontẹ Ọba tẹ Ẹgbẹ na; ati wipe nitotọ ni o ri wọn ni Ile iṣẹ awọn Ọga Onilẹ, (Lands Office) ati wipe, on riwe ipinu ati ti Ofin (Memorandum and Articles) Ẹgbẹ mi na. Lati fi jẹri riro niti enia, Ọlọrun ni Oluṣe pe toto lori wa, ẹda iwe ti a ri gba nigbana nipa rẹ lati ọwọ Ọga Olontẹ Ẹgbẹ Registrar of Company ni a kọ si isalẹ yi.

No. R/C.A. 5/1927.

Lands Department,
Lagos, Southern Nigeria,
10th February.

Igbajọ Auxiliary Union and General Trading Association.

Sir,

I have the honour to acknowledge the receipt of your letter, No. 1/1927 of the 7th instant and to inform you that the Memorandum and Articles of Association of the above Union cannot be registered in its present form under the Companies Ordinance.

I have the honour to be,
Sir,
Your obedient Servant,
(Sgd) H. B. Shepheard.
for Register of Companies.

J. O. O. Ketiku Esq.,
107, Tokunboh Street,
Lagos.

Nitotọ si ni orukọ Ẹgbẹ mi na tori ni ẹjọ to ri i (The Igbajọ Auxiliary Union and General Trading Association, of Nigeria) Owo ko to lọwọ. Iwe Adehun ko dara to.

Inu Ẹgbẹ mi ati Emi na yio dun bi ẹnikẹni ba le ran Ẹgbẹ mi lọwọ iyekiye kan, nitoripe Igba Pọnun la nfẹ si (£200 is wanted).

Mo dupẹ aye to fun mi yi o.

Emi ni tirẹ nitotọ,
B. S. ỌMỌNIJỌ,
Akọwe Agba, fun Igbajọ Union.

---

## PUZZLES.

1. What is that which is full of holes and yet holds water?
2. Which is one of the longest words in the English language?
3. Why is a bridegroom often more expensive than a bride?
4. Who was Jonah's tutor?
5. What belongs to yourself but is used by your friends more than by yourself?
6. What is that which touches one but unites two?
7. What is that which you and every living person have seen, but can never see again?
8. What word is that, to which if you add a syllable, it will be shorter?
9. What is the smallest bridge in the world?
10. Why are fixed stars like pens, ink and paper?
11. At what time of the day was Adam born?

## EKO AKETE

EKO, SATURDAY, MARCH 17, 1928.


### O DE IBI T' O NDE IYAWO OKE 'TẸ.

Nigbakugba ni a nsọ ti inira ailefẹnusọ ti awọn Olotu wa nfi fun wa nipa ofin owo asingba *( Income Tax )* ti nwọn sọ ti nwọn si npalẹmọ lilo rẹ titi oṣu ti o mbọ; ofin yi ko ni ṣai mu idamu pupọ ati aibalẹ ọkan wa fun pupọ ara ilu, ninu eyiti a nwi yi si ni a tun ri awọn Wọnlẹ-wọnlẹ Ijọba ti nwọn nṣiṣẹ kita nipa wiwọn ilu Eko fun mimuṣẹ Ofin Tito Eko *( Lagos Town Planning Ordinance )*, ohun ti a si gbọ ni fẹnrẹn nipa eyi wipe ọgọrọ ile ni ofin na yio ba wi ni ti pe ki awọn onile na wo wọn tabi ki nwọn tun wọn kọ; a si tun gbọ agbọsọ kan pe ọna yio jẹ ile Sanmari kan eyiti Bọkini na ti fi ogidinleje owo pọnun kọ ni kikọ-atata. ti Ijọba ba tilẹ ni awọn fẹ gba irufẹ ile bẹ ti Ọgbẹni na ti kọ ni ile Wasimi, ati pe awọn yio si sanwo rẹ fun, nibo ni Ijọba yio tun fũn ni igboro Eko yi ti 'yio to fun Ọgbẹni yi lati tun fi kọ'le ramuramu ti o ti kọ ri? Tabi Ijọba le sọ pe awọn le tun fun ni ilẹ nibo miran lati kọ'le si, ti yio si ma sanwo *( leasehold )* le ori ilẹ na fun Ijọba, nigbana ni a o to ri iran wo; kini ko jẹ ki inu awọn ilu dun si awọn ile kotopo-kotopo bi ile-imi ti Ijọba kọ si Yaba, a ṣebi nigbati Ijọba ni awọn yio fi haya fun awọn ti nwọn ba nfẹ ni kàkà ki nwọn tã; nigbakugba awọn Oyinbo miran kĩ ye sọ pe awa Enia Dudu ni o ni ilẹ apa tiwa nibi, ati pe awọn kan nba wa tọju rẹ ni: Ṣiọ, titcju gbaguda wo niyen? Irufẹ ede ti awọn Oyinbo miran nlo yi ki ṣai mu ni ranti owe wa kan ti o sọ pe Aṣ'ọgbọn pa aguntan jẹ Ila, o ni oju aguntan nba on l'ẹru; ki a sọ gasikia fun ara wa, sisin bi ẹru ni gbogbo siso ofin ani-ni-lara wọnyi jẹ loju ọpọlọpọ enia; eyiti a si tun gbọ ti o ṣo ni lọwọ ni pe a sọ pe Ijọba si dawọ fifi aṣẹ fun awọn to fẹ pilẹ kọ'le si Suru Lere duro; njẹ eyi ko de 'bi t' o nde iyawo Oke 'tẹ bayi? Bawo aye ha fun l'Eko ti o si tiraka ti o ra ilẹ diẹ si Suru Lere ti o si fẹ pa agọ sibẹ ni gbigbe ti ko si tun si aye fũn lati ṣe iṣẹ ile na, kini ki oluwarẹ yio ba ara rẹ ṣe o? Ẹnyin ilu, a ma nke to, kàkà ki inira wọnyi buku npele lo npele si, nitotọ o le ṣe "gbẹdẹ" fun ọgọrọ awọn ẹlomiran, ṣugbọn awọn nkan le fun nisisiyi, ati jẹ ati mu lo po ju ofin wo ni Ijọba le sọ pe awọn fẹ so loni ti ko ni wọ'lẹ, bi nwọn bã ti l'ogi nwọn a fi l'ẹkọrọ, bi Ijọba fi Iwe Ikedo sita loni pe awọn fẹ gba gbogbo ilẹ ti o wa ni Ita Tinubu fun iṣẹ-ilu, ki nwọn si sanwo fun awọn ti o ba nile nibẹ, ara wo ni a le da iwe-irohin le sọ sọ sọ tobẹ ki tadã fẹrẹ ta lẹnu kalamu, ṣugbọn asan ni, ẹnyin ko ṣakiyesi iṣẹ nlanla ti awọn Aṣoju wa mẹtẹta ṣe pẹlu awọn Oyinbo diẹ ti nwọn ki iṣe Oniṣẹ Ọba ni Ajọ Igbimọ Aṣofin, ki ofin owo asingba ki o ma le di oriṣa, ki o si di ohun akunlẹ-bọ, pabó ha kọ, kini o le da Gomina Agba duro lati tun yan Ọgbẹni Atapaniganku si Ajọ Igbimọ Aṣofin lati je Aṣoju Idi-Iroko, gẹgẹbi o ti yan Ọgbẹni kan ni lọlọyi lai fi ti ẹnikọkan ṣe bikoṣe ti Ọba King?

Ilu, ẹ jigiri, ki ẹ si mu iṣẹ adura ṣe, ọrọ ode isisiyi ko jẹ bẹ: Ijọba igba lailai ko mu pakanleke ofin lilelile bayi dani, gbogbo nkan tù, o si bà, owo nṣan bi omi, iṣẹ ko si wọn ẹnikẹni, òwò tan kalẹ rẹrẹ bi ejinrin, ṣugbọn loni nkọ?

Ẹniti o fi oju ana wo'ku,
Ẹbọra a bọ l'aṣọ.

---

PUBLICATION RECEIVED.

Catalogue of "White's Native Remedies" by Victor White, Esq., the well-known African Chemist of this town.

Mr. White's effective medicines on sale at 41, Offin Road, Lagos, are used all over the world.

# ỌLỌRUN MAṢE JẸ KI A RI MUSIBA!

[ WOSIKA LATI ỌWỌ ATARI AJANAKU ]

Mo bẹrẹ f'oji

Ẹnikẹni ti • ba la'wọ diẹ, ti o fun Onibara tabi Alumọngeri ni odidi Kọbọ aladọjọ loni, odidi Kọbọ eladọjọ l'ọla, Gari l'ọtunla, ati oniruru nkan miran, yio ti ma gbọ oniruru adura ti awọn Onibara nṣe, yio si ti ṣe alabapade Onibara kan pataki ti o nṣe adura nigbagbogbo bayi wipe, " Ki Ọlọrun jọwọ maṣe jẹ ki a ri Asara, ki O ma si ṣe jẹ ki a ri Musiba !

Gbogbo wa ni o mọ wipe t'ẹgbọn-t'aburo ni Asara ati Musiba; ati wipe, Gbin-gbin-ni-kin, a-wuwo bi atẹ ibanujẹ ni baba awọn mejeji. Ile ti nwọn ba wà, ariwo yio ta nibẹ: ilu ti nwọn ba si sọ ẹru wọn kalẹ si, patapata ni ilu na yio di ahoro. Asara, Musiba, ki Baba maṣe jẹ ki eyikeyi ninu awọn mejeji fi ara han ni ilu wa, tabi ni ile ẹnikẹni ninu wa.

Ṣugbọn, anu ṣẹ wa pupọ lati sọ wipe, nigbati a ba ranti ofin miran ti Munisipa ( *Municipal Department*) nṣe, a fẹrẹ le wipe Musiba ni awọn Oyinbo npe ni Munisipa fun wa. Ṣile mẹwa ti a nsan lori Basikulu (*Bicycle*) kọkan l'ọdun ni ko to Musiba ni, tabi Pọnwun mẹwa, Ṣile mẹwa lori Gbọkọkan?

Munisipa ko le le Yanmuyanmu kuro ni ilu, bẹni nwọn ko gbọdọ ri Tanwiji ni ile ẹnikẹni, nwọn ko bere bi enia ti o ninu omi Ilo ti pọ to ni ile kan, bi ile papa ba ti tobi to, ni nwọn ma fi gba Owo-ile, eyiti nwọn npe ni Owo-omi; Ewurẹ ko gbọdọ jẹ ni gbangba, bẹni ko gbọdọ jẹ ni kọrọ, o di kiko.

Aroye awọn Elewurẹ ti a tun ngbọ nisisiyi ni o jẹ ki a tun gb'ẹnu le ọrọ ti a ti sọ ri nipasẹ Ewurẹ kiko, ati pe bi ika ko ti dọgba, ati bẹ bẹ lọ.

Bi ika ọwọ ko ti dọgba jalẹ, bẹni ipo enia ni aiye ju ara wọn lọ, o si ṣoro pupọ ki gbogbo wa to le ma ṣe iṣẹ kanna. Bi gbogbo ilu ba kọ iṣẹ Dokita, ko si ẹniti yio ri owo fi jẹun ninu gbogbo wọn: bẹni gbogbo wa ko le jẹ Lọya tan, ki a si wipe ẹjọ-ẹlẹjọ ṣa ni a o ma ro, bi igbati obi nku si ọran-ọlọran.

A fẹ, a kọ; Kapinta, Telọ, Akọwe, Alaru, Oniṣowo ati Agbẹ ni lati wa ni arin wa, bẹni a ko le fẹ ẹniti yio ma sin Adiẹ, Tolotolo, Ewurẹ tabi Ohun-ọsin miran ku ninu wa.

Ewurẹ jẹ ohun-ọsin pataki fun pupọ ninu awọn arugbo wa; Mọrẹnikẹ nṣ'oge, iya rẹ np'atọ bi ẹlẹdẹ-odo, enia pọ to wọbu ni Eko. Bi o ba ri iya ẹlomiran ti o we lawani ti o funfun ju yinyin lọ, tabi ki Kọla rẹ ga ju inṣi mẹta (*3 inches*) lọ, oju yio ti ọ. Eko nikan, boya, ni a le ri ọpọlọpọ ọmọ ti ko bikita fun iya wọn, papa, bi iya na ba tubọ lọ jẹ ẹniti o nro aṣọ, ọmọ rẹ ko ni fẹ ki ẹnikẹni mọ wipe iya on ni o nṣe; bi iya ẹlomiran ba si jaja ni owo diẹ lọwọ, adura ki o ku, ki o ku, ni ọmọ rẹ yio ma ṣe ni ojojumọ, nitori ki o le ri ogun jẹ.

Ninu ikoko dudu ni ẹkọ funfun ti njade wa, ọmọkọmọ, ibaṣe ọkunrin tabi obinrin ti o ba ntiju, tabi ki o ṣe alaibikita fun iya rẹ, nitoripe on jẹ gbajumọ, ati wipe iya on jẹ mẹkunnu, ti ko si bu ọla fun baba rẹ pẹlu, irufẹ ọmọ bẹ nfi a-da-bi ti o buru ju epe lọ ṣ'ere ni; nikẹhin ni yio si mọ wipe a ko nri ẹbọ abamọ ṣe !

Njẹ, ko ha yẹ ki irufẹ iya ti ko ni olutọju bayi, ti o si ti d'agba ju ẹniti awọn *boys* le ṣẹju si, wa ohun ti yio ṣe fun Onjẹ ọjọ rẹ? Tabi, tani le kilọ fun u wipe ko gbọdọ sin Ewurẹ, eyiti o le ma ko ọmọ rẹ ta ni ọdọdun ni Ọbun Eko? Ẹniti o ri nkan jẹ papa nsin Ewurẹ, ki a ma ṣẹṣẹ sọ ti ẹniti ko jẹun anọ sun.

Ṣugbọn ati sin Ewurẹ ko to ati ri owo san lati fi gba a silẹ nigbakugba ti awọn Ọmọ-eriwo ba mu u!

Ọpọlọpọ ni ko mọ ohun ti Ewurẹ ṣe, ti o fi di ọta Oyinbo loni. Kini Ewurẹ ṣe? Ẹnikẹni, ti Ewurẹ ba gbe Oni-kẹkẹ-ologere (*Bicycle*) tabi Mọto (*Motor car*) papa ṣubu loju rẹ lẹkanṣoṣo, yio mọ ohun ti Ewurẹ ṣe, ti o fi di ọta Oyinbo. Fun anfani awa papa, ewu pupọ ni o wa ninu pe ki Ewurẹ ma jẹ li ọna awọn Opopo-nla, bi Ẹhin-gbẹti, Ẹhin-ọgba ati Titi (*Streets*) miran ti o tẹju gbalasa; nitorina, Ewurẹ-k'ewurẹ ti o ba jẹ larin awọn Opopo-nla wọnyi, nkan-ki-nkan ti o ba ri nibẹ, ko nṣe ẹjọ ẹnikan!

Eyiti ko ye wa rara nibẹ ni wipe, ki nwọn ma mu Ewurẹ ni ọdẹdẹ oluwa rẹ, tabi kakiri kọrọ adugbo miran ti Mọto ko n-aba gba nigbagbogbo, gẹgẹ bi a ti ngbọ. A si tun gbọ ẹwẹ, wipe, ọpọlọpọ enia ti nwọn mu Ewurẹ wọn ni ko tun nri wọn gba pada mọ, bi nwọn tilẹ mu owo lọ si ibiti a ko wọn si, nitorina, o yẹ ki Ijọba tabi awọn Munisipa kilọ daradara fun awọn ti o nko Ewurẹ kiri, ki nwọn maṣe tun mu Ewurẹ ni ọdẹdẹ oluwa rẹ mọ, ki nwọn si ma fi awọn ti o ba njẹ ni kọrọ adugbo kekeke silẹ ni alafia, ki awọn arugbo wa gbogbo le ma ri owo ida'kọ-mu ararọ lori wọn.

Ninu gbogbo ofin Ijọba tabi ofin ilu wọny sibẹ, ko yẹ ki a gbagbe awọn talaka rara; talaka l'o pọju ni ilu; ati l'aisi wọn, ẹwẹ, kini owo le ṣe?

Onile ko gbọdọ tun ile kọ, onilẹ ko gbọdọ kọ ile ti o wu u sori ilẹ rẹ, afi eyiti o ba wu Munisipa, enia ko gbọdọ pa ẹran jẹ ni ile rẹ lasan lai san owo fun wọn, Ọkọ ko gbọdọ rin loju omi lai san owo fun wọn, obinrin ko gbọdọ kọ Buka, ki o p'atẹ siwaju ile ọkọ rẹ lai san owo fun wọn, enia

# NOTHING BUT TRUTH.

## Banish away your rheumatism by using

## "WALK EASY ANTI-RHEUMATIC SALTS"

(EGBOGI LAKUREGBE AJE-BI-IDAN)

Sold only by:—

**K. B. SAVAGE,**

IYIN OLUWA MEDICINE STORE,
88, Broad Street, Lagos.

---

VIBRONA
VIBRONA
VIBRONA

# WINE

Refreshes the strong
Restores the weak
Revives the depressed

**The Highest Medical Authorities say so!**

Local Representative:—

**K. B. SAVAGE, Esq.**

*Head Office:*—88, Broad Street,
*Branches at:*—6, Martins Street,
41, Alli Street, Faji Market,
109, Griffith Street, Ebute-Metta.


Disinfectant Soap of Unrivalled Quality
Use Magnet Carbolic Soap in your home—it refreshes the skin and guards against infection. Made in three sizes, and obtainable everywhere.
MAGNET
Carbolic Soap Tablets
MAGNET
SOAP
WEST AFRICAN SOAP COMPANY LIMITED. APAPA.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH ).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by Victor White, Esq., *The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—Not Obtainable Elsewhere.
"Shake the Bottle."

### AREMO FUN OKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Șugbọn nigba pupọ ni o njẹ pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo arun ti ki ẹ ki ọkunrin șe abiamọ.

*N.B.*—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loșoșu—Ișẹ ti egbogi na nșe ni ara ko șe royin.

Price Ten Shillings ( 10s ) per bottle.

*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic.

A splended Remedy for Female diseases such as :—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by Victor White Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B :—Not obtainable elsewhere.*

### GBOGBONIȘE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ, ati orișirisi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

Price 10/- Per Bottle.
**Postage 2/6 extra.**

WHITE'S
## WONDERFUL BRAIN TONIC

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq
41, Offin Road, Lagos.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.

N.B.—*Scholars should not be without it.*

### EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe șișẹ ati gbogbo awọn ti o ba a lati lọ fun idanwo.

*Iba șe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*( A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy or Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by
Victor White, Esq , *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos
"SHAKE THE BOTTLE".

Price Ten Shillings ( 10/- ) per bottle.

*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

### EGBOGI ILANA ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupo fun obinrin ti ko ba r nkan oșu rẹ mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Așẹ Ewurẹ pipọju, Ẹda ti o ba gba Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyun Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to:—

MR. MOSES O. COKER,

Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
(Manchester) Limited,
65, George Street,
Manchester.

---

GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic: has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same,* if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

---

*Cable Address*:—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIREMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

Indents House.

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.

---

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

---

TO LET.

One Splendid Pleasure Car

No. L2754.

**Always at everybody's service at Tinubu Square.**

For Terms, Apply to:—

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

# ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

—— : o : ——

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọm..
ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to k..
si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aşetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi a..
awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si f..
ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.